**COMMUNITY AUDIT REPORT 2018**

**ÀKÓJỌPỌ̀ ÀBÁJÁDE IṢẸ́ AYẸ̀WÉ-OWÓ-WÒ ÀGBÀ LÓRÍ ÈTÒ ÌṢÚNÁ ÌJỌBA ÌPÍNLẸ̀ ÈKÌTÌ FÚN ỌDÚN 2018**

## 1.0 ÀMÚLÒ ÈTÒ ÌṢÚNÁ

- Ètò ìṣúná ọdún 2018 jẹ́ ètò ìṣúná èyí tí owó tó wọlé àti owó- ìná yóò jẹ́dọ́gba-n-dọ́gba iye owó tía lérò pé yóò lé ní ọgọ́rùn-ún lé mẹ́jọ Bílíọ̀nù Náírà (₦108,538,072,813.52).

- Owó tó wọlé ní ọdún náà lé ní Bílíọ̀nù mẹ́rìn dín lọ́gọ́rin Náírà (₦76,716,106,897.27) nígbà tí owó- ìná lé ní Bílíọ̀nù méjìdín lọ́gọ́rin Náírà (₦78,793,624,355.11), èyí tó túmọ̀ sí pé ànálé owólé ní Bílíọ̀nù méjì Náírà (₦2.077,517,454.84). Owó tó wọlé lé ní ìdáàádọ́rin (70.68%), nígbà tí́ owó ìná lé ní ìdá méjìléláàdọ́rin (72.60%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún

- Owó tó yẹ kó wọlé látigbàdègbà ní ọdún náà lé ní Bílíọ̀nù márùn-ún dín láàádọ́rùn-ún Náírà (₦85,417,450,407.84) èyí tó lé ní ìdá méjì dín lọ́gọ́rin (78.70%) nínúìdá ọgọ́rùn-ún gbogbo owó tó yẹ kó wọlé. Owó tó wọlé lọ́dún náà dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù mẹ́tàdínláàádọ́rin Náírà (₦66,719,055,756.18) èyí tó lé ní ìdá méjì dín lọ́gọ́rin (78.11%)nínú́ ìdá ọgọ́rùn-ún.

- Owó tó yẹ kó wọlé fún àkànṣe-iṣẹ́ ní ọdún náà lé ní Bílíọ̀nù mẹ́tàlélógún Náírà (₦23,120,622,405.68) èyí tó jẹ́ ìdá mọ́kànlélógún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (21.30%) gbogbo owó tó yẹ kó wọlé. Owó tó wọlé fún àkànṣe-iṣẹ́ dín ní Bílíọ̀nù mẹ́wàá Náírà (₦9,997,051,141.08) èyí tó mú àdínkù bá iṣẹ́-àkànṣé tó yẹ ní ṣíṣe nínú ètò ìṣúná ọdún náà sí ìdá mẹ́tàlélógójì nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (43.24%).

- Owó ìná àtigbàdégbà tí a ní lọ́kàn fún níná ní ọdún náà lé ní Bílíọ̀nù mẹ́rinléláàádọ́rinNáírà (₦74,803,953,943.02), èyí tó dín díẹ̀ ní ìdá mọkàndínláàdọ́rin (68.92%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún gbogbo Owó tó yẹ ní níná.Owó tó sì wọlé gan-an dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù mẹ́tàdínláàdọ́rin Náírà (₦66,827,485,978.50) èyí tó lé ní ìdá mọ́kàndínláàdọ́rùn-ún nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (89.34%) ìṣàmúló ètò ìṣúná.

- Owó ìná tí wọ́n ṣe àlàkalẹ̀ láti ná lórí iṣẹ́-àkànṣe ní ọdún náà lé ní Bílíọ̀nù mẹ́tàlélọ́gbọ̀n Náírà (₦33,734,118,870.41), èyító lé díẹ̀ ní ìdá mọ́kànlélọ́gbọ̀n (31.08%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún gbogbo owó tó yẹ ní níná. Iye owó tí wọ́n ná ní pàtó fún àkànṣe-iṣẹ́ ní ọdún náà dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù méjìlá Náírà (₦11,966,138,376.61), èyí tó lé díẹ̀ ní ìdá márùn-dínlógójì (35.47%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún tó sì mú àdínkù bá iṣẹ́-àkànṣe nínú ètò ìṣúná ọdún náà.

- Owó tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́wàá Náírà (₦10,613,496,464.82) tí a lérò pé yóò jẹ́ àjẹṣẹ́kù ní ọdún náà láti san sí àpò ìdàgbàsókè Àkànṣe-iṣẹ́ (CDF) ni kò ṣeéṣe dípò bẹ́ẹ̀, ó lé ní ọgọ́rùn-ún lé méjọ Mílíọ̀nù Naira tí owó ìná àtìgbàdegbà fi ju iye owó tó wọlé (₦108,430,222.32) ní ọdún náà.

- Ètò àlàkalẹ̀ ìnáwó fún àkànṣe sí ìnáwóàtìgbàdegbà jẹ́ ìpínkan sí méjì (ratio 1;2) nígbà́ tí àbájáde èsì jẹ́ìpínkan sí márùn-ún (ratio1;5)

- Ohun tí a rí mú jáde nípa èyínipé a kò lo ètò ìṣúná náà gẹ́gẹ́ bí àlàkalẹ̀ rẹ̀.

## 2.00 ÀKÍYÈSÍ ÀTI ÀBÁ ILÉ IṢẸ́ AYẸ̀WÉ-OWÓ-WÒ ÀGBÀ LÓRÍ ÌṢÀMÚLÒ ÈTÒ ÌṢÚNÁ.

- Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó wò ṣe àkíyèsí pé owó tó ń wọlé láti bí ọdún márùn-ún sí àpò Ìjọba kéré púpọ̀ sí iye tí wọ́n gbèrò pé yóò wọlé. Owó tó dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù mọ́kàndínlọ́gbọ̀n Náírà (₦28,862,479,401.89) tí wọ́n lérò pé yóò wọlé pọ̀ ju iye tó wọlé lọ tí èyí kò jẹ́ kí gbogbo àlàkalẹ̀ inú ètò ìṣúná náà wá sí ìmúṣẹ.

- Èrò Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò nipé àwọn àṣìṣe tó màa ń jeyọnínú ètò ìṣúná ń fa kí èròǹgbà Ìjọba má lè wá sí ìmúṣẹ lórí àlàkalẹ̀ ètò ìṣúná náà.

- Níwọ̀n ìgbà tí Ìjọba ti faramọ́ ètò SFTAS, ó ní àwọn ìdá owókan tí wón níláti yà sọ́tọ̀ fún níná tí wọ́n sì maa ńgbé wọnú ètò ìṣúná tí wọ́n sì gbọ́dọ̀ san. Èyí pè fún ṣíṣe àgbékalẹ̀ ní òkodoro owó-ìná àti owó tó ń wọlé nínú ètò ìṣúná.

- Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò ṣe àkíyèsí pé àdínkù bá owó tó yẹ ní níná fún àkànṣe-iṣẹ́ láti iye owó tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́tàlélọ́gbọ̀n Náírà (₦33,734,118,870.41) sí owó tó lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù mẹ́tàlélógún Náírà (₦23,120,662,405.68) nínú ìwé àtúnyẹ̀wò ètò ìṣúná (IPSAS) tí Ilé-iṣẹ́ tó ń ṣe ètò ìṣúná gbé kalẹ̀ nítorí àtúntò àwọn owó tó ń wọlé láti jẹ́ kó wà ní ìbámu pẹ̀lú ètò NCOA. Eléyì jẹ́ ìdènà fún owó àkànṣe-iṣẹ́ ọdún náà.

- Àṣìṣe ńláyìí wáyé nítorí àìṣe àmúlò àlàkalẹ̀ IPSAS fún ṣíṣe ètò ìṣúná ọdún 2018.Eléyií ṣe àtakò àbájáde àlàkalẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-Owó-Wò ti ọdún 2017.Eléyìi ń fẹ́ àkíyèsí Ilé-Iṣẹ́ Ètò Ìṣúná.

- Ọ̀pọ̀àpapọ̀owó tó wọlé níọdún náà jẹ́ owó láti àpò Ìjọba Àpapọ̀ tó sì jẹ́ iye owó tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́rìnlélàáàdọ́ta Naira (₦54,243,709,566.73) èyí tó lé ní ìdá àádọ́rin nínú ọgọ̀rùn-ún gbogbo owó tó wọlé (70.70%).

- Nípa báyìí,gbogbo akitiyan Ìjọba Ìpínlẹ̀láti mú àdínkù bá gbígbẹ́kẹ̀lé owó tó ń wọlè látọ̀dọ̀ Ìjọba Àpapọ̀ kó tíì múná dóko.Nítorí náà,ó ṣe pàtàkì kí Ìjọba Ìpínlẹ̀ wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣàdá láti ri i pé owó ń wọlé lábẹ́lé

## 2:01 ÌMỌ̀RÀN

- Àgbékalẹ̀ Ìdàgbàsókè Ètò Ọrọ̀ Ajé tó Yànràntì;Ìjọba Ìpínlẹ̀ nílò láti ṣe àgbékalẹ̀ ètò ọlọ́jọ́ pípẹ́ tí yóò jẹ́ mímúṣe ní ẹyẹ ọ̀ sọ́kà.Èyí gbọ́dọ̀ ní àkóònú ètò ọrọ̀ ajé tó yànràntìpẹ̀lú ọ̀nà àbáyọláti mú kí èròǹgbà náà di mímúṣe.Irú ètò báyìí gbọ́dọ̀ jẹ́ àìgbọ́dọ̀máṣe fún Ìjọba tó bá wà lórí àléèfà nítorí èyí yóò jẹ́ kí ìdàgbàsókè ọrọ̀ ajé gbèèrú si i.

- Àwọn owó tó wọlé lásìkò tí owó epo rọ̀bì gbé pẹ́ẹ̀lí sí i nia gbọ́dọ̀ lò fún ìdókòwò láti fi ìpílẹ̀tó yànràntì múlẹ̀ fún ìdàgbásòkè ọrọ̀ ajé ní Ìpínlẹ̀ dípò kí a maa ná irú owó bẹ́ẹ̀ lórí àwọn iṣẹ́ tí kò mú ìdàgbàsókè bá ètò ọrọ̀ ajé Ìpínlẹ̀.

- Ìpínlẹ̀ nílò ètò tí yóò gbéìṣẹ́ àgbẹ̀ lárugẹ fúnìpèsè iṣẹ́ àti ohun èlò ni àwọn ilé iṣẹ́ ńláǹlà tí yóò jẹ́ kí owó tó ń wọlé lábẹ́lè gbé pẹ́ẹ̀lí si i.Kí Ìjọba ṣe àgbèǹde àtí ìgbélárugẹ ìpèsè ìrẹsì Ìgbèmọ̀lọ́nà tó bóde òní mu.

- Àjọṣepọ̀ tó dán mọ́rán gbọ́dọ̀ wà lááàrin Ilé-Iṣẹ́tó jẹ́ ti Ìjọba àti ti Aládàáni fún ìdàgbàsókè ètò ọrọ̀ ajé Ìpínlẹ̀.Kí àgbékalẹ̀ òfin tí yóòfàyè gba ìdásílẹ̀ Ilé-Iṣẹ́ Aládàáni di gbígbé lárugẹ.

- Kí Ìjọba ṣe àfihàn àti ìpolongo àwọn ohun àmúsọrọ̀-ajé Ìpínlẹ̀ yíí fún àgbáyé rí nípa ṣíṣètò ìpàdé àpérò àti ìlanilọ́yẹ̀ lòri ètò ọrọ̀-ajé láti fa ìfẹ́ àwọn olùdáṣẹ́-sílẹ̀ lábẹ́lè àti lókè- òkun wá sí Ìpílẹ̀ yíí.

## 3.0OWÓ TÓ Ń WỌLÉ LÁBẸ́LÈ

- Owó tó wọlé lọ́dún yíí dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù méjìlá Náírà (₦11,949,154,857.67) dípò owó tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́tàlá Náírà(₦13,084,357,901.63) tí alérò pé yóò wọlé tí èyísì lé díẹ̀ ní ìdá mọ́kànléláàádọ́rùn-ún(91.32%)nínú ìdá ọgọ́rùn –ún ètò ìṣúná.Lára owó tó wọlé yíí ni owó tó wọlé lábẹ́lè láti Ilé –Iṣé ńláǹlà tí Ìjọba àti Ilé-Ẹ̀kọ́ Gíga tó lé ni Bílíọ̀nù márùn-ún Náírà (₦5,649,442,542.31) (47.27%)tí èyí tó kù tó le ni Bílíọ̀nù mẹ́fà Náírà (₦6,299,712,315.36)(52.73%)wọlé láti Ilé-Iṣẹ́ tó ń pawó wọlélábẹ́lè (State Internal RevenueService).

- Owó tó wọlé lọ́dún náà fi iye owó tó lé ní Mílíọ̀nù mẹ́tàdín láàádọ́ta Náírà (₦47,300,813.36), gbé pẹ́ẹ̀lí ju ti ọdún tó kọjá. Iye tó fi gbé pẹ́ẹ̀lí síi yìí kéré níye tí àbá fi wé ti àwọn ọdún mẹ́ta wọ̀nyí: ti ọdún 2015 lé ní Bílíọ̀nùkan Náírà (₦1,064,417,745.00), ti ọdún 2016 le ni Bìlíọ̀nù kan Náírà (₦1,077,460,753.13) nígbà tí ti ọdún 2017 lé ní Bílíọ̀nù méjì Náírà (₦2,432,741,819.54).

- Ìdàgbàsókè tó bá owó tó wọlé lábẹ́lè lọ́dọọdún jẹ́ 0.40%. Àdínkù bá àpapọ̀ iye tó ń wọlé lábẹ́lè sì àpapọ̀ owó tó wọlé ní ọdún tó kọjá láti 17.18% sí 15.58% ní ọdún 2018.

- Iye owó tó wọlé lábẹ́lẹ̀ láti àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba (MDAs) lórí(fines) fáínì (owóìtanràn) àti àwọn owó míìràn lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù kan Náírà (₦1,045,264,627.02) pẹ̀lú ìṣàmúlò ètò ìṣúná ìdá 53.56%. Àwọn owó tó wọlé láti ilé-iṣẹ́ Ìjọba (MDAs) mẹ́ta tí iye wọn pọ jùlọ ni (i) Ilé-iṣẹ́ tó ńsètò ilẹ,Igba lé mẹ̀tàlá Mílíọ̀nù Náírà(₦213,352,015.49), (ii) Owó ìdàgbàsókè láti Ilé-Ẹ̀kọ́ jẹ́ Mílíọ̀nù mẹ́sàn-án lé ni ọ̀ọ́dúnrún Náírà (₦309,353,185.00) àtí (iii) owó láti owo-ori fun ìdàgbàsokè ẹ̀kọ́(ETF) lé ní Ọ̀rìnlénígba Mílíọ̀nù Náírà (₦280,828,595.42).

- Àwọn ìsọ̀rí Ilé-iṣẹ́ Ìjọba mẹ́tàlá péré nínú àwọn márùńdínláàádọ́rin tí a gbé jáde nínú ìwé ètò ìṣúná ọdún 2018 ni owó wọn gbé pẹ́ẹ̀lí nínú owó tó wọlé nígbà tí ọ̀pọ̀ nínú àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba (MDAs) kò rí owó pa wọlé. Nípa báyìí, ọ̀pọ̀ owó tí a lérò pé yóò wọlé láti Ilé-iṣẹ́ Ìjọba ni kò wọlé tí kò sì jẹ́ kí ìrètí nípa iye owó tí a lérò pé yóò wọlé lábẹ́lé lè wá sí ìmúṣẹ.

- Àròpọ̀ gbogbo owó-orí tó wọlé ní ọdún náà dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù márùn-ún Náírà (₦4,799,846,715.29) nínú èyí tí owótó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́rin (₦4,193,406,394.50) jẹ́ owó orí tó wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ Ìjọba(PAYE), tó túmọ̀ sí ìdá mẹ́tàdínláàádọ́rùn-ún lé ìpín mẹ́tàdińlógóòjì (87.37%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún.

- Àwọn owó orí tó wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn tí kìíṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba kéré níye ní ọdún náà èyí tó lé ní ìdá mẹ́ta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (3.41%) gbogbo owó-orí tó wọlé tí iye rẹ̀ lé díẹ̀ ní Mílíọ̀nùmẹ́ta lé lọgọ́jọ àbọ̀ Náírà (₦163,583,025.97).

- Gbígba owó-orí láti ọ̀dọ̀ àwọn aráàlú tí kìí ṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba ń jẹ́ kí owó orí tó wọlé sápò Ìjọba gbé péélí sí i. Àwọn Ilé-iṣẹ́ tó ń pawó wọlé lábẹ́lẹ̀ (Internal Revenue Service) gbọ́dọ̀ ṣakitiyan láti rí i pé àwọn aráàlú san owó-orí wọn déédéé.

## 3.01 ÌMỌ̀RÀN/ÀBÁ

- Ètò láti mọ iye àwọn aráàlú tó ń sanwó orí ní Ìpínlẹ̀ yìí yóò jẹ́ kí owó-orí tó ń wọlé lábẹ́lè gbé pẹ́ẹ̀lí sí i. Mímọ iye àwọn tó ń sanwó orí níọ̀pàkùtẹ̀lẹ̀ fún wíwọlé owó-orí lọ́pọ̀ yanturu.

- Ètò "Ọjọ́ Owó-Orí" ni a lè ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ láti dá àwọn tó san owó-orí tó pọ̀jù lọ́lá láti mú ìwúrí bá àwọn ènìyàn kí wọn lè máa sanwó-orí déédéé.

- Ṣíṣe ètò ìtanijí ìta gbangba nípa sísan owó-orí déédéé sí àpò Ìjọba, lílẹ àwòrán áwọn iṣẹ́ tí a fi owó-orí ṣe mọ́ pátákó ajúwe ńlá káàkiri ìgboro fún àwọn ènìyàn láti jẹ́ ọ̀nà ìmóríyá fùn àwọn olùsanwó-orí.

- Ríró àwọn tó ń ṣiṣẹ́ ọwọ̀ lórísirísi lágbára.

- Ṣíṣe ìwúrí fún àwọn Ilé-iṣẹ́ tó ń gbówó orí wọlé kí wọ́n lè nífẹ̀ẹ́ sí iṣẹ́ wọn.

- Àwọn Ilé-iṣẹ́ àti Ilé-Ẹ̀kọ́ tí wọ́n ń yọwó orí òṣìṣé wọn ni a gbọ́dọ̀ pọ̀n-ọ́n ní dandan fún láti maa yọ owó-orí náà ní pípé gẹ́gẹ́ bí Àjọ agbowó-orí ti ṣe àlàkalẹ̀ rẹ̀ láti jẹ́ kí owó-orí tó ń wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ pọ̀ sí i.

- Ṣíṣe àtúnyẹ̀wò iye owó-orí tó yẹ ní sísan látìgbàdégbà.

- Ṣìṣe àgbékalẹ̀ ọ̀nà tó rọrùn láti sanwó-orí bí i sísan lóri fóónù àti àwọn ọ̀nà amáyélujára mìíràn.

## 4.00 FÍFÚN ÀWỌN ILÉ-IṢẸ́ ÌJỌBA NÍ OWÓ-ÌNÁ FÚN LÍLÒ

- Àkíyèsíwa ni pé owó-àfiṣíṣẹ àkànṣe àti owó-ìná tó yẹ fún àwọn Ilé-iṣẹ́ ni kò tẹ̀ wọ́n lọ́wọ́ gẹ́gẹ́ bí àgbékalẹ̀ inú ètò ìṣúná. Àwọn Ilé-iṣé tí a ṣe àlàkalẹ̀ owó bí iye tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́fà (₦6,087,315,737.97) fún ni kò rí owó kànkan gbà ní gbogbo ọdún náà. Àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba (MDAs) mìíràn tó yẹ kó gba owó tó lé ní Bílíọ̀nù méjọ Náírà (₦8,381,632,655.43) ni kò rí gbà ju owó tó

dín díẹ̀ ní Ẹgbẹ̀ta dín màrùn- ún Mílíọ̀nù Náírà (₦554,908,139.46) tó jẹ́ bí i (6.62%) ìdá mẹ́fà àti ìpín méjìlélọ́gọ́ta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún.

- Àwọn owó tí a ti ṣe àlàkalẹ̀ rẹ̀ fún Ilé-iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan yẹ ní sísan fún wọn kí àwọn iṣẹ́ tí wọ́n ti ṣe àlàkalẹ̀ nínú ètò ìṣúná lè di mímúṣe. Eléyìí yóò ṣeéṣe tí Ìjọba bá lè yàgò fún àwọn iṣẹ́ tí àlàkalẹ̀ rẹ̀ kò lè wá sí ìmúṣe.

## 5.00 ṢÍṢE ÀMÓJÚTÓ OWÓ- ÌNÁ

- Aṣe àkíyèsí pé àmójútó wà fún ìnáwó ní ọdún náà nítorí pé àdínkù bá owó ànájù ní àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba gbogbo láti owótó lé ní Bílíọ̀nù méjì (₦2,455,804,133.98) ní ọdún 2017 sí owó tó lé ní Mílíónù mẹ́rìnlélọ́gọ́jọ Náírà (₦164,490,663.87) ní ọdún 2018.

- Àwọn ànájù owó tó wáyé jẹ́ àṣìṣe àwọn òṣìṣẹ́ tó yẹ kó ṣe àyẹ̀wò fínnífínní lóri owó tó yẹ ní níná kí wọ́n tó gbé owó jáde.

- Ó ṣe pàtàkì kí àwọn òṣìṣẹ́ tí ọ̀rọ̀ kàn ṣe àmójútó ètò ìnáwó ní Ìpílẹ̀ yíínítorí èyí ṣe pàtàkì nínú ètò ìṣúná àti bí owó ṣe ń wọlé.

## 6.00 ÀGBÉKALẸ̀ ÈTÒ-ÌNÁWÓ

## 6.01 OWÓ TÓ WÀ NÍLẸ̀ (OWÓ ÀTI ÀWỌN ǸǸKAN ÌSỌDOWÓ)

- Iye owó tó wà lọ́wọ́ àti àjẹṣẹ́kù ní Báǹkì títí di ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n, Oṣù kéjìlá ọdún 2018 dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù méjìlá (₦11,951,237,961.91) èyí tó jẹ́ àpapọ̀ àjẹṣẹ́kù àwọn Ilé-iṣẹ́ àti owó tó wọlé lábẹ́lé.

- Kò sí àjẹṣẹ́kù owó àkópamọ́ (fixed deposit) ní ìparí ọdún ètò ìṣúná náà.

- Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó wò Àgbà ṣe àkíyèsí pé owó tí wọ́n maa ń yọ fún Ìjọba lórí òṣùwọ̀n ọjà títà (VAT)ní oṣù mẹ́ta ni Access Bank kó sínú àṣùwọ̀n ìkówópamọ́sí (fixed deposit) fún ọjọ́ díẹ̀ láì gba àṣẹ lọ́wọ́ Ìjọba. Èlé orí

owónáà tó dín díẹ̀ ní Mílíọ̀nù méjì (₦1,725,405.00) ni kò jẹyọ nínú àkọsílẹ̀ Ilé-iṣẹ́ àmójútó owó Ìjọba (Accountant General's Office).

- Ìmọ̀ràn fun Ilé-iṣẹ tí ń ṣe àmójútó owó Ìjọba Ekiti (Accountant General's Office) nipé kí wọ́n jára mọ́ iṣẹ́ wọn láti rii pé gbogbo owó tó wà nílẹ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ mímúlò lọ́nà tí ó lè mú èrè wá fún Ìjọba.

## 6.02 OWÓYÀÁ (BOND)

- Ìjọba san owóyàá tó jẹ́ ogún Bílíọ̀nù (₦20,000,000,000.00) (ìpín àkọ́kọ́) tó yá ní ọdún 2011. Ìpín owó náà tó jẹ́ ti Ìjọba lé ní Bílíọ̀nùkan (₦1,254,432,000.00) gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹyọ nínú ìwé àṣùwọ̀n owó àkópamọ́ Ìjọba láti san gbèsè ní ìparí ọdún 2018 (31st December 2018).

## 6.03ÀWỌN OHUN ÌNÍ ÀÌṢEÉGBÉ (OHUN ÈLÒ ÀTI IRIN-IṢẸ́)

- Àwọn ohun ìní Ìjọba tí aṣe àròpọ̀ owó rẹ̀ ní ìparí ọdún 2018(31st December, 2018) lé ní Bílíọ̀nù mẹ́tàdínlógún Náírà (₦17,310,868,787.86) lẹ́yìn ìgbà tí a ti ṣe ìdíyelé ìlò rẹ̀ síowó tó dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù méjì Náírà (₦1,872,485,283.79).

- Iye owó àwọn ohun ìní àìṣeégbé Ìjọba àti àwọn nǹkan èlò mìíràn tí wọ́n rà ní ọdún 2017 àti 2018 ni ójẹyọ nínú àwọn àlàkalẹ̀ ètò ìnáwó ti ọdún náà.

- Ọdún kan péré ló kù fún Ìjọba lẹ́yìn sáà kejì àbájáde ètò ìnáwó yìí láti ṣe àkọsílẹ̀ ìdíyelé àti ìdámọ̀ gbogbo ohun ìní rẹ̀ nínú àbájáde ètò ìnáwó.

- Ìwé àkọsílẹ̀ lórí ohun ìní Ìjọba pàtàkì pàtàkì tí a ṣe àlàkalẹ̀ rẹ̀ ní ìlànà IPSAS ni Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò kò ì tíì ṣe alábápàde rẹ̀. Kí Ilé-iṣẹ́ tó ń ṣe àmójútó ohun ìní Ìjọba ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ fún àyẹ̀wò.

## 6.04 ÀWỌN GBÈSÈ ÌJỌBA FÚN SÍSAN PADÀ LỌ́WỌ́LỌ́WỌ́

- Àròpọ̀ gbogbo gbèsè tí Ìjọba jẹ títí di ọjọ́ kọ́kànlélọ́gbọ̀n òṣu kéjìlá ọdún 2018(31st December 2018) lé ní Bílíọ̀nù mẹ́rìnlélógúnNáírà (₦24,317,230,789.73)

- Ó jẹ́ ẹ̀dùn ọkàn pé Ilé-iṣẹ́ tó ń ṣe àmójútó owó Ìjọba (Acoountant General's Office) kò ṣe akitiyan láti ṣe àwárí àti ìdámọ̀ àwọn ìwé àkọsílè gbèsè tí Ìjọba jẹ, bó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n mọ̀pé ó jẹ́ ọ̀nà àbáyọ sí gbígbàá wọlé sí IPSAS.

- Pẹ̀lú gbogbo ìmọ̀ràn Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó wò Àgbà ní ọdún 2017, gbogbo gbèsè tí Ìjọba jẹ lórí ìpèsè ohun ẹ̀ṣọ́ ilé, owó tí wọ́n jẹ àwọn Ilé-iṣẹ́ àti owó gbà-má-binú ni wọn kò nááni nínú àbájáde ètò ìnáwó 2018.

- Gẹ́gẹ́bí a ti ṣe àkíyèsí rẹ̀ nínú àkọsílẹ̀ tó jáde láti Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó wò Àgbà ti ọdún tó kọjá, Ilé-iṣẹ́ tó ń ṣe àmójútó owó Ìjọba kò tíì ṣe ìwé àkọsílẹ̀ gbèsè Ìjọba títí di ọjọ́ kọkànlélọ́gbọ̀n oṣù kéjìlá ọdún 2018 (31st Dec 2018).

## 6.05 ÀWỌN GBÈSÈ FÚN SÍSAN PADÀ LỌ́JỌ́IWÁJÚ (OWÓYÀÁ ỌLỌ́JỌ́ PÍPẸ́)

- Àròpọ̀ gbèsè tàbí owóyàá ọlọ́jọ́ pípẹ́ tí Ìjọba jẹ ní ìparí oṣú kéjìlá ọdún 2018 lé ní Bílíọ̀nù méjìdín láàádọ́rùn-ùn Náírà (N88,101,923,330.15). Owóyàá láti òkèèrè lé ní ọgbọ̀n Bílíọ̀nù Náírà (N30,034,529,853.59) nígbà tí owóyàá lábẹ́lé lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù méjì dín lọ́gọ́ta Náírà (N58,067,393,476.56)

- Àròpọ̀ owóyàá láti òkèèrè àti lábẹ́le tí wọ́n gbà ní ọdún náà dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù mẹ́wàá Náírà (₦9,997,051,141.08). (owòyàá lábẹ́lé dín ní ọ̀ọ́dúnrún Mílíọ̀nù Náírà (₦287,500,000.00) tí owòyàá láti òkèèrè sì dín ní Bílíọ̀nù mẹ́wàá Náírà (₦9,709,551,141.08).

- Gbogbo owóyàá tí wọ́n san padà ní ọdún náà lé ní Bílíọ̀nù méjìláNáírà (₦12,119,145,413.92) (owóyàá lábẹ́lẹ̀ lé Mílíọ̀nùmọ́kànlá àbọ̀ Náírà(₦11,504,425,721.71) tí owóyàá láti òkèèrè sì jẹ́ẹ́gbẹ̀ta lẹ́ mẹ́rìnlá Mílíọ̀nù Náírà (₦614,719,692.21) Owó tí wọ́n san padà lé ní Bílíọ̀nù méje

Náírà (₦7,288,322,497.76) (60.12%) tí èlé tí wọ́n san lé owó náà sì dín díẹ̀ ní Bílíọ̀nù márùn-ún Náírà (₦4,830,822,916.16) (39.88%).

- A ṣe àkíyèsí pé àwọn owó tí Ìjọba gbà lọ́wọ̀ Báǹkì Àgbáyé fún àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí (i) YESSO (ii)PSGRDP ni kò tíì jẹyọ nínú àbájáde ètò ìnáwó.

- Ohun tí wọ́n fi owóyàá tí ilé-iṣẹ́ 'Fosterfield Limited' gbà lórúkọ Ìjọbani wọn kò lò fùn ǹnkan tí wọ́n gbà á fún.

- Àpapọ̀ gbogbo owó tí iýe rẹ̀ din díẹ̀ ní ọ̀tàlélọ̀ọ̀dúnrún Mílíọ̀nù Náírà (₦359,890,382.36) tí wọ́n yọ fún oṣù mẹ́rin lórí owóyàá ní Access(ECA) ní Access Bank sọ di sísan padà lọ́jọ iwájú. Ìwé àṣẹ láti yọ owó náàni wọn kò fún Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó wò Àgbà.

- Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó wò ṣe àkíyèsí pé ní ìparí ọdún 2018 gbèsè tí Ìjọba jẹ sí owó tó wọlé tí a bá gbé lé òṣùwọ̀n ìdá ọgọ́rùn-ún jẹ́ 146%. Eléyìí ga kọjá àgbékalẹ̀ ìdá àádọ́ta (50%) tí(DMO) Àjọ tó ń ṣe ètò owóyàá ṣe àlàkalẹ̀ láti ṣe ìdúró fún owóyàá. Tí owó tó ń wọlé bá kéré níye, gbèsè sísan padà kò ní rọrùn.

## 7.00 ÀSÌLÒ ÀLÀKALẸ̀ OWÓ-ÌNÁ

- Àlèébù lílo àlàkalẹ̀ ètò ìṣúná ti tẹ́lẹ̀ jẹ́ àṣìlò àlàkalẹ̀ owó-ìná. Ní ọdún tí a ń ṣiṣẹ́ lórírẹ̀yìí, owó-ìná fún àkànṣe-iṣẹ́ tí iye rẹ̀ lé ni Bílíọ̀nù kan Náírà (₦1,278,714,605.90) èyí tó kéré níye sí àlàkalẹ́ IPSAS fún PPE ni wọ́n ná. Láti má jẹ́ kí irú èyí wáyé,àlàkalẹ́ ètò ìṣúná tuntun tó wà ní ìbámu pẹ̀lúàgbékalẹ̀ (National Charts of Accounts) ni kí wọ́n múlò fún àgbékalẹ̀ ètò ìṣúná ọdún 2019 àti lọ́jọ́ iwájú.

## 8.00 ÌDÁMỌ̀ OHUN ÌNÍ ÌJỌBA

- Kí Ìjọba ṣe ìdámọ̀ àti àkọsílẹ̀ tó péye lórí àwọn ohun ìní rẹ̀ láti lè jẹ́ kí ó jẹyọ nínú ètò ìṣúná ní ìparí oṣù kéjìlá ọdún 2019. Eléyìí kò ní jẹ́ kí wọ́n ṣe ìdápadà èrè ti Ìjọba nípa gbígba ìlànà ètò ìṣúná ti IPSAS.

## 9.00 ÀWỌN OWÓ TÍ A GBÀ WỌLÉ LÁTI ÌJỌBA ÌBÍLẸ̀

- Owó tí àpapọ̀ rẹ̀ jẹ́ okòóléníġba àti márùn-ún Mílíọ̀nù Náírà (₦225,000,000) tí ó wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn Ìjọba Ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí owó ìdá tiwọn fún ètò ìdáàbòbò àwùjọ nípasẹ̀ SJLGA ni kò jẹyọ nínú ètò ìṣúná ọdún 2018.

- Àwọn owó tó wọlé láti SJLGA sí Ilé-Iṣé Ìjọba Ìbílẹ̀ (Ministry of Local Governments), Ilé-iṣé tó ń mójú tó ètò ìnáwó Ìjọba (Accountant-General's Office) àti Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó ti Ìjọba Ìbílẹ̀ (Auditor-General for LG) tí iye rẹ̀ lé níỌ̀kànlélọ́gọ́rùn-ún Mílíọ̀nù Náírà ( ₦101,343,618.08),Mílíọ̀nù méjìlélógún ó lé díẹ̀ (₦22,008,967.57) àti Mílíọ̀nù méjìlélógún ó lé díẹ̀ (₦22,008,967.57) ní ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé ni kò jẹyọ nínú àkọsílẹ̀ owó tó wọlé ní ọdún 2018.

- Owó tó wọlé àti bí wọ́n ṣe ná an kò jẹyọ nínú ètò ìṣúnáọdún 2018, kò sí àfihàn rẹ̀ nínú ètò ìnáwó awon Ilé- iṣẹ́ Ìjọba(MDAs). Kíkùnà láti ṣe òkodoro àlàyé lórí owó tó wọlé àti bí wọ́n ṣe ná an lè jẹ́ kí àgbékalẹ̀ ètò ìnáwó má kún ojú ìwọ̀n.

- Àwọn òṣìṣẹ́ tí ọ̀rọ̀ yìí kàn ní àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba (MDAs) níláti fi tó Ilé-iṣẹ́ tó ń ṣètò ìṣúná àwọn owó tó wọlé ní ọ̀dọ̀ wọn.

- A pe àkíyèsí àwọn òṣìṣẹ́ tó wà nípa ètò ìṣúná láti jẹ́ kí àwọn owó tó wọlé náà jẹyọ nínú ìwé-ètò ìṣúná nígbà tí wọ́n bá ń ṣe àlàkalẹ̀ àti àgbéyẹ̀wọ̀ ètò ìṣúná.

## 10.00ÌDÁMẸ́WÀÁ ÌPÍN OWÓ FÚN ÌJỌBA ÌBÍLẸ̀ LÁTI INÚ OWÓ TÓWỌLÉLÁBẸ́LÉ

- Ìjọba Ìbílẹ̀ ní ẹ̀tọ́ sí ìdámẹ́wàá owó tó ń wọlé lábẹ́lé. Ìdámẹ́wàá owó tó wọlé lọ́dún tí à ń ṣiṣẹ́ lórí rẹ̀ tí iye rẹ̀ dín díẹ̀ ní Ẹgbẹ̀ta lé lọ́gbọ̀n Mílíọ̀nù Náírà (₦629,971,231.54) ni a kò rí àkọọ́lẹ̀ pé wọ́n san án fún àwọn Ìjọba Ìbílẹ̀.

- Ṣíṣe ìgbọ́ran sí òfin yìí yóò mú ìdàgbàsókè àti ìlọsíwájú bá agbègbè àwọn Ìjọba Ìbílẹ̀.

## 11.00 ÀWỌN OWÓ TÓ WỌLÉ LÁBẸ̀LÈ TÍ KÒ JẸYỌ NÍNÚ ÀKỌ́Ọ́LẸ̀

- Pẹ̀lú gbogbo atótónu tí a ti ṣe nínú àwọn àbájáde láti Ilé-iṣé Ayẹ̀wé-owó wò Àgbà pé kí gbogbo àkọ́ọ́lẹ̀ lórí owó tó wọlé lábẹ́lẹ̀ wọlésí ọ̀dọ̀ SIRS fún àkọ́ọ́lẹ̀ àti gbogbo Ilé-iṣé tó ń pawó wọlé lábẹ́lé ní Ìpínlẹ̀ yìí ní oṣooṣù tàbí lóṣù mẹ́tamẹ́ta ni kò di mímúṣe. Tí àwọn owó tó wọlé lábẹ́lẹ̀ kan kò bá di sísan sí ibi tó yẹ, ó túmọ̀ sí wí pé wọ́n ná owó náà lọ́nà tí kò tọ́.

- Ṣíṣe àkọ́ọ́lè tó péye gbogbo owó tó wọlé lábẹ́lè yóò jẹ́ kí a mọ òkodoro iye owó tó wọlé.

## 12.00OWÓ TÓ SỌNÙ

- Iye owó tó lé ní ọgọ́rún-ùn léméje Mílíọ́nùNáírà(₦107,384,799.20) tíó sọnù ní àwọn Ilé-iṣẹ́ Ìjọba tí ọ̀rọ̀ kàn ni wọn kò kọbi ara sí. Àwọn Ilé-iṣẹ́ tó ń ṣètò ìnáwó ní àwọn Ilé-iṣẹ́Ìjọba náà kò tilẹ̀ gbé ìgbésẹ̀ láti ṣàwárí owó náà.

## 13.00TÍTA ÀWỌN NǸKAN ÀLÒKÙ ÌJỌBA

- Àbájáde àwọn Àjọ tó ń ṣe àyẹ̀wò lórí títa ohun ìní Ìjọba láti Ilé Ìgbìmọ̀ Aṣòfin ni wọn kò mú wá sí Ilé-iṣẹ́ wa láti ọdún 2016.

- Kí Olùdarí ètò ìṣàkóso àwọn ohun èlò Ìjọba (DAS) ní ilé Ìgbìmọ̀ Aṣòfin fi ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àkọ́ọ́lẹ̀ lórí ohun èlò Ìjọba tí wọ́n tà sọwọ́ sí Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò Ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkìtì láìfi àkókó ṣòfò.

## 14.00 SÍSAN GBÈSÈ GBOGBOGBÒÒ TÍ ÌJỌBA JẸ

- Gbésé tí Ìjọba jẹ lórí àjẹ́mọ́nú owó ohun ẹ̀sọ́ ilé ni kò jẹyọ nínú àkọ́ọ́lè owó-oṣù àti àwọn àjẹmọ́nú míiràn tí Ìjọba kò tíì san tí Ilé-iṣẹ́ tó ń ṣe àmójútó ìnáwó Ìjọba gbé jáde. Ó ṣe pàtàkì láti wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣàdá láti san àwọn gbèsè wọ̀nyí kí ó má báá ma peléke sii.

- Kí àwọn owó tó ti yẹ kí wọn san di sísan, kí wọ́n sì san èyí tí Ìjọba jẹ tẹ́lẹ̀ kí Ìjọba yíí tó dé orí àléèfà. Tí òṣìṣé bá ti ń fẹ̀yìn tì lẹ́nu iṣẹ́, kí wọ́n maa san owó àjẹmọ́nú wọn, kí gbèsè má túbọ̀ maa pọ̀ si i.

- Ní èrò tiwa, sísan gbèsè tí Ìjọba jẹ yóò ní ipa rere lórí ìṣèjọba nítorí àwọn ènìyàn tí wọ́n sanwó fún yóò ní inú rere sí Ìjọba, wọn yóò sì lo owó náà láti gbé ètò ọrọ̀ ajé Ìpínlẹ̀ Èkìtì lárugẹ. Bákan náà ni yóò mú àdínkù bá wàhálà lórí à ń san owó ìfẹ̀yìntì tó ti kórajọ torí pé ó rọrùn láti sanwó fún àwọn ènìyàn péréte lóṣooṣù ju kí wọ́n san àkójọpọ̀ owó ìfẹ̀yìntì tóti kórajọ gègèrè fún ọ̀pọ̀ ọdún.

## 15.00 YÍYỌ OWÓ-ORÍ BÍ ÀWỌN ÒṢÌṢẸ́ ṢE Ń GBOWÓ OṢÙ

- Àwọn Òṣìṣẹ́ Ilé-Ẹ̀kọ́Gíga nì Ípínlẹ̀ Èkìtì kò tẹ̀lé òfin yíyọ owó orí ti 2011 (Personal Income Tax Act 2011, PITA). Èyí mú àdínkù bá owó-orí tó yẹ kó wọlé lábẹ́lé. Tí òfin yíyọ owó-orí àwọn òṣìṣẹ́ bá di mímúlò lọ́kùnkúndùn, owó-orí tó yẹ kó wọlé sí àpò Ìjọba láti Yunifásítì Ìpínlẹ̀ Èkìtì yóò lé ní Mílíọ̀nù méjìlélógún (₦22,000,000) nígbà ti ti àwọn Ilé-Ẹ̀kọ́ Gíga tí Ìjọba yóókù yóò lé ní ọgọ́rin Mílíọ̀nù (₦80,000,000) lóṣooṣù.

- Owó-orí àwọn òṣìṣẹ́ Ilé-Ẹ̀kọ́ Gíga ni ó gbọ́dọ̀ di yíyọ ní pípé gẹ́gẹ́ bí àgbékalẹ̀ òfin owó-orí yíyọ (Personal Income Tax Act 2011, PITA) láti jẹ́ kí owó tó ń wọlé lábẹ́lẹ̀ ní Ìpínlẹ̀ Èkìtì lè gbé pẹ́ẹ̀lí sí i

## 16.00 ÀWỌN IṢẸ́ ÀKÀNṢE TÓTI DI ÀKỌ́TÌ

- Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò Àgbà ṣe àkíyèsí pé àwọn iṣẹ́ àkànṣe tí a ti kọ̀tì tẹ́lẹ̀ni iṣẹ́ ti gbérasọ lórí wọn báyìí. Yàtọ̀ sí ànfààní tí ṣíṣe àwọn iṣé yìí á mú ba ọrọ̀-ajé Ìpínlẹ̀, owó gegere tí àìparí àwọn iṣẹ́ naa lásìkò yóò gbé lérí yóò jẹ́ ẹrù ńlá fún Ìpínlẹ̀ lọ́jọ́ iwájú. Nítorí náà, kí Ìjọba ṣakitiyan láti parí gbogbo iṣẹ́ àkànṣe tó wà nílẹ̀.
- **A dábàá pé:**
  - (i) Ọjà tí wọn ó ti maa ta àwọn ẹ̀yàaraọkọ̀ àti irin-iṣẹ́ tó wà lọ́na Pólì ni kí wọ́n fún àwọn tí yóò máa tajà níbẹ̀ láti kọ́ fúnra wọn.
  - (ii) Kí a ya iye kan sọ́tọ̀ nínú ètò ìṣúná Ìjọba láti fi parí àwọn iṣẹ́ àkànṣe tí wọn kò tíì parí.

## 17.00ÀWỌN ẸKA ILÉ-IṢẸ́ ÌJỌBA TÍ A KÒ ṢE ÀYẸ̀WÒ ÌWÉ ÈTÒÌNÁWÓWỌN

- Pẹ̀lú gbogbo àríwísí tí a ṣe nínú ìwé àbájáde àkọ́ọ́lẹ̀ Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò Àgbà, ìwé ètò ìnáwó àwọn ẹ̀ká Ilé-iṣẹ́Ìjọba wọ̀nyíí ni a kò ì tíì yẹ̀wò.

(i) State Universal Basic Education Board (Àjọ tó ń ṣètò Ẹ̀kọ́ Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀)
(ii) Ekiti State Electricity Board (Àjọ tó ń ṣètò iná-mọ̀nàmọ́ná)
(iii) Ekiti State Water Corporation (Àjọ tó ń ṣetò omi-ẹ̀rọ)
(iv) Fountain Holdings Ltd (Ilé-iṣẹ́ Aládàáni ti Ìjọba)
(v) Ekiti State Housing Corporation (Àjọ tó ń ṣètò Ilé)
(vi) Ekiti State Sports Council (Àjọ tó ń ṣètò Eré Ìdárayá)

## 18.00ÀWỌN OHUN TÓ Ń FẸ́ ÀMÓJÚTÓ NÍ ILE- IṢẸ́ AYẸ̀WÉ-OWÓ-WÒÀGBÀ TI ÌPÍNLẸ̀ ÈKÌTÌ.

i. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti Ìdàgbàsókè àwọn òṣìṣẹ́
ii. Ètò ìnáwó.
iii. Òfin Ayẹ̀wé-owó-wò
iv. Ọkọ̀ àfiṣiṣẹ́
v. Ilé-iṣẹ́(Ọ́fíìsì) fún àwọn òṣìṣẹ́
vi. Ipò tí àwọn òṣìṣẹ́ wà

## 19.00GBÈSÈLÓRÍ ỌKỌ̀ TÍ ÌJỌBA GBÉ FÚN ÀWỌN OLÓṢÈLÚ TÓ TI KÚRÒ LÓRÍ ÀLÉÉFÀ.

- Iye owó tó dín díẹ̀ ní Ọ̀ọ́dúnrún lé mẹ́rìnlélọ́gbọ̀n Mílíọ̀nùNáírà(N333,701,122.62) ni gbèsè tówà nílẹ̀ lórí ọkọ̀ tí ìjọba gbé fún àwọn olóṣèlú náà. Ìmọ̀ràn fún Ìjọba ni pé kí wọ́n maa yọ owó náà lóṣooṣù nínú owó-oṣù àwọn tó ṣì di ipò òṣèlú mú nínú iṣèjọba tó wà lórí àlèéfà láti lè san ìyókù owó náà padà.

- Àwọn tí kò sì di ipò òṣèlúkankan mú nínú iṣèjọba tó wà lórí àlèéfà ni kí wọ́n yọ ìyókù owó tí wọ́n jẹ nínú owó gbà-má-bínú tí Ìjọba ṣì jẹ wọ́n.

## 20.00 ÌṢÀKÓSO PÀFÍLÍỌ̀NÙ (PAVILION) NÍ Ọ̀NÀ ÌYÌN TUNTUN

- Owó tó ń wọlé láti Pàfílíọ̀nù Ìjọba ni a ṣe àkíyèsí pé wọn kò san wọlé sí Ófíìsì Ilé-iṣẹ́ tó ń ṣètò ìnáwóÌjọba (Accountant General's Office), kò sì jẹyọ nínú Ìkànnì SIRS (SIRS Portal).

- Àwọn ìwé rìsíìtì tí wọ́n fi ń gbowó lọ́wọ́ àwọn tó ń lo sọ́ọ̀bù tó wà ní Pàfílíọ̀nù náà tí Olùsakóso ètò ìnáwó Ìjọba (DFA) sọ pé wọn kò mọ̀ nípa rẹ̀ ni a kò rí fún àyẹ̀wò.

## 21.00 ILÉÌTURA TI ÌJỌBA

- Ìwáádì tì Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó wò Àgbà ṣe fihàn wípé àwọn ènìyàn kan ń gbé ní Ilé Ìtura Ìjọba láìsan owó sí àpò Ìjọba láti gbé ọrọ̀-ajé Ìpínlẹ̀ yíí láruge.

- Ilé-iṣẹ́ yíí ṣe àkíyèsí pé, pẹ̀lú gbogbo Ilégbèé tó wà nínú ọgbà Ilé Ìjọba àti gbogbo ohun mèremère tí wọ́n ṣe sínú rẹ̀, tí kò sì sí ẹni tó ń gbé ibẹ̀, ọ̀pọ̀ àwọn àlejò Ìjọba ni wọ́n ń gba Ilé-ìtura Aládàáni fún tí wọ́n sì ń san owó gegere síbẹ̀.

Daniel . A Kayode (FCNA,FCFIP,ACTI)
FRC/2014/ANAN/00000010277
Auditor-General,
Ekiti-State.